“Ẹni ti o ba lọ onigbese lára, tabi ti o ba a din in ku tabi ki o ni ki o ma san an mọ́, Ọlọhun maa fi i sábẹ́ ibòji Ìtẹ́-ọlá Rẹ ni Ọjọ́ Àjínde, ni ọjọ́ ti ko nii si ibòji kankan àyàfi ibòji Rẹ”

Láti ọdọ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Òjíṣẹ́ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe: “Ẹni ti o ba lọ onigbese lára, tabi ti o ba a din in ku tabi ki o ni ki o ma san an mọ́, Ọlọhun maa fi i sábẹ́ ibòji Ìtẹ́-ọlá Rẹ ni Ọjọ́ Àjínde, ni ọjọ́ ti ko nii si ibòji kankan àyàfi ibòji Rẹ”.

[O ni alaafia] [Tirmiziy ati Ahmad ni wọn gba a wa]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé ẹni tí o ba lọ onigbese lára, tabi ti o ba a din gbese rẹ ku, ẹsan rẹ ni pe: Ọlọhun maa fi i sábẹ́ ibòji Itẹ-ọla Rẹ ni Ọjọ́ Àjínde ti oorun maa sunmọ orí àwọn ẹrú ti ooru rẹ si maa lágbára, Ẹni kankan ko nii ri ibòji àyàfi ẹni tí Ọlọhun ba fi si abẹ ibòji.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/4186